To The Chief Secretary to the Govt


# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead.

Vol. VI. No. 262 SATURDAY, FEBRUARY 18, 1928. 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.



## White's Radical Gonkiller.

:o:

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases, such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs,** and sold only by

Victor White, Esq., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

Price: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI

:o:

[ *Fun Atọsi lailai ati titun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si nję ki o ri aye wu arun mi silę.


23 FEB. 1928

ni Ile

A. Tijọ Olu

Akin Adesigbin

"AWA O MA JO, AWA O MA YO, NI"

Aga ati Asia (*Flags*) ti Germany lorişirişi wa fun hihaya ni No. 3, Docemo Street, Lagos. Aga ati Asia wọnyi dara fun akẹkẹyẹyẹ pupọ, fun Igbeyawo Wolimọ, Ijọ-Ọdun Musulumi, tabi ti Kiriyo, fun ere nile Ẹgbẹ, ati orişirişi ohun ayọ miran.

*Terms very moderate*

for particulars, please apply at :—

EKO-ATORO CHAIRS & FLAGS SUPPLY

*Office* :—

No. 3, Docemo Street,
P.O. Box No. 505.
Lagos, Nigeria.

**Coffins to suit your Taste.**

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at J. B. da Silva, 40, Odunlami Street, Lagos: also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

# Ero ya wa ra

ADEBOYE ŞOLANKẸ Onişowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikan-ọkọ, Işo lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Ọşan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa ’okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Şọbu rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Ọlowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-işẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

**Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ.**

**Are you a Mechanic ?**—If so you must want Tools, now or soon.

**Do you intend to put up a house?**—Then you will require Builder's Hardware.

In either case you cannot do better than call at

**B. C. Vaughan's "Excelsior" Stores**

at Agarawu Street, Lagos.

Where the largest and most varied assortment of Artisan's Tools and Building Materials in Lagos is stocked.

Quality to satisfy all demands, and prices to suit all pockets.

*Special discount to Traders and Wholesale buyers.*

**J. C. VAUGHAN**

Ti ile ọja Sheffield ni ita Kakawa ati ile-ọja *Excelsior* ni ita Agarawu ni orişirişi ati oniruru ohun kikọ 'le fun tita ni owo-ọpọku-ọyọku.

Ilẹkun awọn ile-owo mejeji wọnyi şi silẹ fun awọn Ọmọle ati awọn Gbẹnagbẹna : bi o fẹ awo ni o, ero-ija dida'wo ko ni jẹ ọ ni'ya lati ra nibẹ :

Alagbẹdẹ Wura tabi ti Fadaka ni ọ ni o, gbe l'oşe fun ọ lati re yan irin-işẹ tirẹ nibẹ ba kanna.

Owo Ọgbẹni J. C. Vaughan ti di Owo Ab... Ajanaku lọjọ to ti pẹ : bi Ọgẹdẹ si ni Owo rẹ ng kakiri ibikibi. Agbẹ ni ọ kai ! bi o ri orişirişi O... ti o ri ra nibẹ ha yio şe ọ.

Sure tete iwọ Ọmọle, iwọ Gbẹnagbẹna, iwọ Aranbata, iwọ Asenjẹ iwọ Ageginigbo (Sawyer), Alagbẹdẹ Wura, iwọ Alagbẹdẹ Fadaka, iwọ A... re ba ori're tirẹ pade nibẹ.

Owo-lọwọ ni gbogbo ọja meremere nibẹ.

*Editor & Proprietor:*—
ADEOYE DENIGA,
*Office 24*, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

E fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

### IYAWO ỌLẸ D'AGBA!

Ọgọrọ iyawo ni a ṣakiyesi pe awọn Musulumi ngbe nisisiyi ninu eyiti oṣu Awẹ nku fẹfẹ, a gbọ fẹnrẹn pe ọgọrọ awọn ọmọge ti nwọn to gbe ni nwọn nle ọkọ afẹsọna wọn lere pe ki nwọn tete ṣe botijẹ nipa mimura ati ṣe inawo iyawo wọn, bi bẹkọ, owe oke yi ko ni ṣai ṣẹ si irufẹ awọn ọkọ afẹsọna ti nwọn ba jafara ati ṣe "kokari" fifi owo dabira. bẹ lara

### ỌPỌ NI EṢU FI NYA IGI.

Ọgọrọ orukọ awọn ti nwọn ti fi orukọ na silẹ lati dibo fun Aṣoju Eko mẹta ninu Igbimọ Aṣofin Nigeria ni a ri ka ninu *Gazette* li ọjọ kẹsan oṣu yi, a gbọ pe ninu oṣu *October* ọdunni ni didibo na yio ya.

### ONILU KO NI JẸ O TU.

O ta si wa leti wipe ogidigbo iwẹ-ẹbẹ ti ẹgbẹ Dẹmọ npete lati fi ṣọwọ si Sẹkitẹri Agba ti ilu Oyinbo nipasẹ ọran owo asingba (*Income Tax*) ngbaradi nisisiyi, gẹgẹbi ipinnu ti ẹgbẹ ṣe ni ipade ọjọ 14 oṣu to kọja; ẹnyin ara ilu, ẹ maṣe jafara lati tọwọ bọ ọ, ti nwọn ba kan si nyin, boya awọn Mọlayika a jẹ ṣe "to!"

### ẸNYIN AKẸRAN IṢẸ DE!

Gbogbo ilu lo gbojikan lati arin ọsẹ to kọja wipe awọn wonpari kan ṣẹṣẹ da si ilu lati ma ki awọn ọmọ kekeke mọlẹ lọ ta ni idalẹ. A sọ fun ni wipe ọmọ ti olukuluku nwa nisisiyi ti nwọn koi ti ri wọn fẹrẹ to meje, ọran na mu wa l'omi, ẹnyin Alabojuto Ọpa Ọba.

## IJỌBA MẸTA NI ILU EKO.

Otito jẹ on ti o koro pupọ, ṣugbọn ko si ẹniti ko mọ, Eṣu papa ninu ọrun apandi mọ ohun ti otitọ jẹ Ibẹru ki i jẹ ka sọ otitọ, Agabagebe pẹlu a ma fẹ lati pa otitọ loku nitori on nfẹ lati jẹ ti ẹni lagbaja nitorina ko jẹ sọ otitọ jade, nitori ki lagbaja ko ma ba binu si on ṣugbọn ibikibi ti otitọ ba wa gẹgẹ bi efin ninu ile ni yio han si ode dajudaju.

Gbogbo ilu lo mọ ni gbangban pe Ijọba mẹta lo wa ni Ilu Eko yi loni.

Ekini—Ijọba Gẹsi
Ekeji—Ijọba Oniṣowo
Ẹkẹta—Ijọba Ṣọṣi

Ijọba Gẹsi—Dansaki, agba lọwọ ẹni, o jẹ Ijọba ti gbogbo ilu fẹran nitoriti o nba wa lara mu, ṣugbọn nisisiyi, gbogbo wa li o nfi irọju dupẹ lọwọ wọn, nigbati wọn ba mu ofin kobakungbe le wa lori, Eti nwọn a si kọ gbogbo ẹbẹ wa, eyikeyi to wun ko jẹ lati mu iru ofin bẹ kuro lọdọ wa.

Awọn lo kọkọ npe wa ni ọrẹ wọn, ati gẹgẹ bi ọrẹ ti le ṣe si ọrẹ rẹ, bẹni awa nfẹ lati ma ṣe si wọn, nwọn ṣe sumọ,—bẹni ọrọ alafia ni nwọn kọkọ pe ọrọ wọn fun wa ṣugbọn nisisiyi o ti di ọrọ lẹbẹlẹbẹ. Lati aiye lailai ni Ijọba Enia Dudu ti buru, ṣugbọn awọn alagbara wọn ṣe sumọ, nwọn a si ma gbọ ohuntiti o ba ndun ọmọ ẹhin tabi ọmọ abẹ wọn, nwọn ki si saba ma ṣe ika nigbagbogbo, nitori ilẹ ti nwọn ntẹ, wọni "ti o ba laya ko ṣeka ṣugbọn ti o ba ranti iku Ga ko ṣe otọ." Ijọba Gẹsi dara pupọ, ṣugbọn ofin lile miran ko ṣai si.

### IJỌBA ONIṢOWO.

Nigbati a ba mu ijọba gẹsi tan, atun ni lati mu ti awọn oniṣowo pẹlu nitori awo ni ngbe awo ni gbọwọ ni awọn mejeji nṣe awọn Oniṣowo Gẹsi lo njọba lori gbogbo ọja ti o wa ninu ilu Yoruba ati ti ilẹ Hausa pẹlu, ti a ba ti mu on jijẹ kuro, gbogbo eyiti Oyinbo nra lọwọ wa ni nwọn njọba le lori patapata. Bi o ti buru to ni, ọja eyiti

nwọn nra lọwọ wa, gbogbo wọn lo nso ipanpa pọ le wa lori, iye ti wọn ba si fẹ lati ra lọwọ wa ni wọn ma nsan afi ata, alubọsa, Ẹfọ ati iru nkan miran eyi ti a nra jẹ lọwọ ara wa ni awọn enia wa le diyele, ti wọn si ni lati ta ni iye ti yio fi pe fun wọn şugbọn nkan bi Ẹpo agba, Ekurọ, Coffee, Cocoa, Ẹpa, Awọ, Rubber, Gẹdu, ati nkan miran ti Oyinbo ngba lọwọ wọn yala o ri ere jẹ lori rẹ tabi o ko ri ere jẹ ni o, yala o ri oju owo tabi o ko ri oju owo ni o, awọn onişowo ko fẹ lati mọ, iye ti nwọn ba fẹ lati san ni nwọn ma ra lọwọ oninkan lori ọja tiwọn eyi ti nwọn nta ni Şọbu kẹ, iye ti nwọn ba fẹ ni awọn tun nta fun wa, nwọn a si ta ni ọna eyi ti awọn enia tiwa, ti wọn nşe owo pẹpẹpẹ ko ni le fi ri ere tẹ nibẹ, depo pe siga ti wọn nmu, ere tọrọ pere lo wa ninu mejila, bẹni wọn le ta ni şile mẹdogun tabi pọun kan fun mejila, tabi ko tun din ju bẹ lọ, şugbọn nigbati nwọn ri pe gbogbo ilu lo nmu siga nwọn duro lori şile meji le tọrọ fun ọkan, bawo ni a ti le şe owo iru eyi ti a le fi ri owo ra onjẹ; ki a san owo omi, owo po, Owo ita, Owo atupa pẹlu owo ori ati ti dukia eyi ti a şẹşẹ tun fẹ gba lọwọ wa nisisiyi, ati owo pẹpẹpẹ miran gbogbo eyi ti a nsan fun ijọba loni—nwọn ngba ere ti nkan Oko wa, nwọn si tun gba ere nkan ti wọn nta fun wa pẹlu, ti wọn jẹ ọna meji bẹni awa ko ri ikan jẹ tan ninu mejeji wọnyi, bi wọn ba npolowo akọwe ti ẹnikan ba mu iwe işẹ de ọdọ wọn, iyẹn ni lati mu iwe ile rẹ lọ fun iduro, lẹhin igbati nwọn ba ti bu owo pupọ le ọja wọn lori tan, nwọn a ni ko gbọdọ ta ọja awin sode, nwọn a si tun wi fun pe afi ti o ba le ta ọdunrun pọun silẹ ki o to le ri kọmişọn lẹhin na, ati pe pọun mẹta ni owo rẹ loşoşu, nigbati akọwe na ko ba ta nitori ọja to wọn pupọ iyẹn a bẹrẹ si ta lawin alagbeda a si gbe owo rẹ lọ nigbati kei ti bẹrẹ si ta awin ti wọn ba wa ka ọja ti wọn ba nba ni pipe, nwọn a bẹrẹ si bawi pe ko mọ owo şe, iye bayi ni lagbaja ma nta, awọn a yọ kuro nibẹ, Akọwe ti ko si fẹ ki wọn yọ on a wa bẹrẹ si i ta awin, nigbati o ba si da gbese inu wọn a wa dun lati pe lẹjọ ki wọn ba le ta ile rẹ, ati lati fi gbogbo awọn oni duro rẹ si Wahala, wọn ni ko si eyi ti o kan awọn nibẹ nitori "bi ọgọ ta, bi ọgọ ko ta, owo alaru a pe" iyẹn ni fi wọn bẹ.

## IJỌBA ŞỌŞI.

Ijọba yi ni nina saba nşaju awọn mejeji ti a ka s'oke iwe yi, nwọn dabi iranşẹ tabi atnn-ọna iwaju şe fun awọn ti nbọ lẹ'hin awọn ni i ma şaju Ijọba lati tu ọkan awọn enia ilu ati lati se ọkan wọn rọ, nigbati Ogun ba de si wọn nwọn a kọ wọn lati ta Asia funfun wọn a ma wasu agbara ti oyinbo ni, wọn a si ma fi ọrọ Ọlọrun kọ wọn wipe bi wọn ba jiya l'aiye yi wọn a ri ere popo jẹ l'ọrun nibiti gbogbo wọn nlọ nigbati wọn ba ku.

Lẹhin igbati idi wọn ba ti ran ilẹ tan awọn pẹlu ijọba ni lati pin ikogun, wọn a bu ilẹ onilẹ fun wọn falafala, wọn a kọ Şọşi wọn a wa bẹrẹ s[i] owo lọwọ awọn enia gẹgẹ bi ti ijọba; şugbọn jẹ tipatipa ekeji jẹ ti ekute a jẹ ni fẹni, ko [...] yala o ji ni wọn ko fẹ mọ şa mu wa yala o [...] wọn ko fẹ mọ, şa mu wa, Ọlọrun a fun o ni mẹwa, wọn ko şi şabu, o ko ba wọn [...] şugbọn wọn a ma şiro gbese si ẹ l'ọrun, [...] owo Kilasi, ọtọ ni owo Tikiti, ọtọ ni owo Alufa, ọtọ ni owo ọdun, ọtọ ni ti ijoko, [...] idawo arọ, ọtọ ni idawo alẹ, ọtọ ni owo [...] joko ni ile ọtọ ni idawo ẹniti o wa ni idalẹ, [...] eyi ti wọn o fi tun ile Ọlọrun şe, ọtọ ni eyi t[i] o fi tun şukuru şe, pupọ Alufa wọn li o d[...] ti wọn ran ọmọ wọn lọ si ilu Ọba, nibo ni iwọ mẹmba ti wọn ni ki o ma mu wa, wa o[...]

Ijọba kan owo ti wọn gba lọwọ wa nipa, [...] ki o fi inu didun mu ti ẹ wa, awa ko kan nip[...] diẹ ti to, kọbọ kan li ọsẹ ko ma san si kilasi [...] meji fun şọşi ti alẹ ati ti arọ, kọbọ kan [...] Alufa kọbọ kan fun tikiti, kọbọ kan On[...] Oluwa, ko si ma fi bi iwọn şile kan pamọ [...] gbogbo lati san owo ti yio yọ si ẹ li ojiji, nitori Ọdun Bibeli ba de ko yẹ ki o ma ni owo [...] idanwo pataki ba de orukọ rẹ lo yẹ ko wa ni [...] awọn ẹlomiran sọ mẹmba di ero ẹhin şugbọn [...] miran nra ile kun ile ati oko kun oko, gbo[...] nkan ti awọn onigbagbọ ti aiye awọn Ap[...] lailai, ti ta, awọn enia wa lo nra wọn [...] Igbagbọ ti lailai yatọ pupọ si ti ode Eko wa [...] o dun mi pupọ ti a ko le tun ji X dide [...] tun wa wo awọn ọrọrọ ni ile Ọlọrun loni, [...] iba a bajẹ pupọ lati ri pe ki işe awọn me[...] nikanşoşo ni X ati X mọ şugbọn [...] aşaju ijọ awọn ti a ro pe wọn o ma fi ọna han awọn ọ[...]n na ni X papa ti wọn da'k[...] nwọn sin Tolo-Tolo, Pẹpẹyẹ, Adiẹ ati nkan [...] gbogbo; ti nwọn njẹ, ti nwọn nmu, gbogbo [...] ni X iba bawi, nitori ikuna wọn, "bẹ la [...] Kristi kọ nyin."

Otọ şoro sọ pupọ, gbogbo ijọ li o mọ [...] gbogbo ti a ti nwi şiwaju gbogbo ilu lo si m[...] iha ti ijọba kọ si on loni, Ọkunrin pup[ọ] Onişowo ti pa l'oku ati pupọ ninu wọn lo w[a] ile ẹwọn loni nigbati owo ti wọn fun wọn [...] na, bẹni a koi ti ri Şọşi kan ti o wasu pe ow[o] tabi owo dukia yi ko dara, nitori ki Ijọba m[...] da awọn na duro lẹnu işẹ wọn nipa [...] gbogbo wọn nlo p'irẹ si koto kana; şugbọn [...] o da wa loju nibẹ ni pe, "Ọlorun ni yio daj[ọ] ẹhin pin ẹran."

JALANKATO.

ORI II.

## IWA—AGBARA TI ĘKỌ ILE NI.

*(Translated from "Character by Dr. Smiles").*

APA KỌKANLA.

Nigbati Adams, ęniti o ti jẹ oye President ilu America ri, lọ si ibi idanwo ni ile-iwe awọn ọmọbinrin ni Boston, awọn ọmọ ile-iwe na fun ni iwe iyẹsi, ninu eyiti nwọn kọ gbogbo ọrọ ti nwọn fẹ sọ fun si; ọrọ inu iwe na mu lọkan pupọ. Ninu esi ti o fun wọn, o mu ẹnu kan ti agbara ajẹbọwaba ti ẹkọ ti obinrin ti kọ on, ni lori iwa ati igbesi aiye on. O ni, "Ni ọmọde on ni anfani boya, eyiti o tobi julọ ti enia le ni—eyini ti iya ti o ni ayan ti o si to lati kọ awọn ọmọ rẹ ni iwa rere. Ękọk'ẹkọ ti mo le ni, awọn eyiti o si di iwa mi lati kekere de igba ogbo, (papa lọna ęsin ati ti iwa hihu), ọdọ rẹ ni mo kọ wọn—Nko so pe mo kọ wọn pe perepere bi mba ti kọ wọn, şugbọn ti nko ba ni puro mọ oku ọrun, ęniti mo kan sara si, bi aidara kan ba wa ninu iwa mi, tabi bi iyapa kan ba wa kuro lọna ti o tọ mi si, ęiọ ti emi ni ki işe ti iya mi."

Ifẹ ti awọn ọmọ Wesley ni fun awọn obi wọn jẹ lọna ti iwa mimọ ti nwọn jogun lọwọ wọn: şugbọn ọgbọn ati iwa iya wọn ni o di ara fun wọn, ki işe ti baba wọn. Alewi-leşe ni baba wọn, şugbọn n gbamiran a ma kanra, a si ma hu iwa ika si obinrin rẹ ati awọn ọmọ rẹ; ni ti iya won, pęlu ọgbọn ati otitọ inu ni ifi ba wọn lo, ni ifi mu wọn gba tirẹ, ni ifi fi ifẹ ti o ni fun wọn han, ni isi fi şe jẹ pęlu wọn. On ni olukọ ati ọrẹ awọn ọmọ rẹ kęrękęrę awọn na si mu iwa rẹ.

Ọna ti o gba kọ wọn ni ęsin, ni o mu wọn ni iwa lati kekere, eyiti a fi npe wọn ni Eleto *(Methodists)*. Ninu iwe kan, eyiti o kọ si ọmọ rẹ, Samuel Wesley, nigbati o wa ni ile-iwe ni Westminster ni ọdun 1709, o ni, "Imọran mi ni pe ki o ni ọna eto pataki kan *(certain method)*, eyiti o ma fi şe gbogbo işẹ rẹ, nipa şişe eyi gbogbo akoko ni iwọ yio lo ni ọna rere, gbogbo işẹ ti o ba nşe ni yio si rọ ọ lọrun wọkuwọku." Ninu iwe na o rọ ọ, o ni "ọna eto" ti on nsọ yi ni pe, "ki ohun gbogbo ti o ba şe jẹ lori ero tabi ilana;" a si ro pe ęgbę ti awọn t'ęgbọn t'aburo mejeji, John ati Charles, da silẹ ni Oxford, awọn imọran ti iya wọn gba wọn yi ni o jẹ pataki ohun ti o şe okunfa rẹ.

Ni ti awọn ọkọwe-orin, awọn ọmọwe ati awọn ti nşe işẹ ọna *(artists)*, ero ọkan ati ęwu iya, laisi tabitabi, ni agbara nla lori ękọ awọn ọmọ wọn; eyi si fi ara han papa ninu igbesi aiye Gray, Thompson, Scott, Southey, Bulwer, Schiller ati Gœthe.

Baba Gray jẹ onikanra ati oşonu enia. Şugbon inu-ire ati iwa pęlę ti Gray ni, ọwọ iya rẹ ni o fęrẹ jogun gbogbo rẹ. Ni gaskia, ọkọnrin bi obinrin ni Gray—o ni ojuti, ko bę, ko si ni itara tabi akanloju— şugbọn ko si alebu kan bi dudu ori ekuna ninu igbesi aiye rẹ ati ninu iwa rẹ.

Iya ọkọwe-orin yi, lẹhin igbati ọkọ rẹ, enia lasan, ti kọ ọ ti, ti o salọ, on ni o ngbọ ati jẹ ati mu on ati awọn ọmọ rẹ; nigbati o ku, Gray kọ iwe akọle kan si ori orori rẹ ni Stoke Poges, ninu eyiti o sọ nipa rẹ pe "Abiyamọ ti o mọ ęwọn, ti o ni ifẹ; iya awọn ọmọ pupọ, ọkanşoşo ninu wọn ni o şe oriburuku gbẹhin rẹ." A sin ọkọwe-orin na papa, gęgębi ifẹ ọkan rẹ, si ęgbę iboji iya rẹ.

Ọgbọn ati iwa Goethe ọwọ iya rẹ ni o ti jogun wọn bakanna bi ti Schiller. Ębun iya rẹ ko lęgbę. Ọrọ kun ęnu rẹ bi wọbu, o si mọ ọna ti a fi mu ati ewe ati agba gbọn, a ma mu lati inu ogunlọgọ oye ti o ti ko jọ, fi kọ wọn bi a ti işe aiye. Lẹhin ti on ati alejo kan ti jijọ sọrọ kanrin, alejo na gbadun ọrọ rẹ, o si sọ pe, "o wa ye mi wayi eredi rẹ ti Goethe fi jẹ irufẹ enia ti o jẹ." Goethe papa ko gbagbe iya rẹ, ko ye jẹ ę lẹnu. Nijọ kan nigbati o nsọrọ rẹ, o ni, "O wa aiye ni, ko sin wọn wa", nigbati o si lọ si Frankfort, o wa gbogbo awọn enia ti o şe iya rẹ lore ni awakan, o si şopę lọwọ wọn.

Iya Ary Scheffer—ęniti ọmọ rẹ fẹran tobę ti o fi aworan oju rẹ ti o lęwa ya awọn aworan ti Beartrice, St. Monica ati awọn

miran ti o ya—on ni o gba ọmọ rẹ ni iyanju iṣẹ ọna-oju ti o kọ, nipa sisẹ ara rẹ gidigidi, o si ba a wa owo lati kọ iṣẹ na siwaju. Nigbati o ngbe Dordrecht ni ilu Holland, o kọ fi ṣọwọ si Lille ki o lọ kọ iṣẹ nibẹ, lẹhinna o ran lọ si Paris; awọn iwe ti o si nkọ ranṣẹ si ọmọ ni idalẹ kun fun awọn imọran ti o jina hanun, eyiti o jẹ eyiti iya ẹni le fun ni, ati ãjo lọna ifẹ eyiti obinrin ni lọwọ.

Ninu ọkan ninu awọn iwe ti o fi ranṣẹ si, o ni, "Bi o ba ṣe pe iwọ le ri mi bi mo ti nfi ẹnu ko aworan re lẹnu, lẹhinna, pẹlu omi ni oju mi, ti mo gbe aworan rẹ dani, ti mo npe ọ 'ọmọ mi olufẹ', nigbana ni o le ye ọ bi o ti ndun mi lọkan to nigbamiran, ninu iwe mi si ọ ti mo ba nfi dandan-gbọn le ọrọ kan fun ọ, ti mo ba si mu ọ banujẹ x x x Mura si iṣẹ rẹ—ju gbogbo rẹ lọ, baralẹ ki o si tẹriba; bi o ba si ri pe o nta awọn ẹlomiran yọ ninu iṣẹ, nigbana fi iṣẹ-kiṣẹ ti o ba ṣe we eyiti Ọlọrun da tabi ki o fi we eyiti ọkan rẹ mu bi apẹrẹ, iyatọ ti iwọ yio si ṣe akiyesi ninu fifi mejeji we ara wọn, ki yio jẹ ki o bọ sinu ewu igberaga ati ti pe iwọ ni o gbọn ju."

Lọdun gbọrọ lẹhin eyi, nigbati Ary Scheffer tikararẹ ti ri ọmọ-ọmọ rẹ, ko gbagbe imọran iya rẹ, on na si tun fun awọn ọmọ rẹ ni imọran kanna.

Bayi ni a ri i pe agbara apẹrẹ rere a ma wa lati iran de iran, ki i jẹ ki aiye di ogbo.

Nigbati o nkọ iwe si ọmọ rẹ obinrin, Madame Marjolin, ni ọdun 1846, o ranti imọran ologbe iya rẹ, o ni, "Gbolohun ọrọ kan yi DANDAN—maṣe gbagbe rẹ ọmọ mi ọwọn; iya rẹ agba ki i saba gbagbe rẹ. Eredi rẹ ni pe, ninu igbesi aiye wa ko si ohun kan ti imu eso rere wa afi ere ti a ba jẹ nipa iṣẹ ti a fi ọwọ ẹni ṣe tabi eyiti a tirãka fi sisẹ-ara-ẹni ṣe, lai fa gun lọ titi, bi awa ba nfẹ irọra ati anfani, a ko gbọdọ dẹkun fifi ti ara ẹni silẹ gbọ ti ẹlomiran. Nisisiyi ti agba d , ki nsọ otitọ fun ọ, nigbati mo ba nranti awọn ohun wọnni ti mo ti ṣe, awọn eyiti imu inu mi dun ni nigbati mo fi ti ara mi silẹ gbọ ti ẹlomiran, tabi ti mo sẹ ara mi ti mo kọ igbadun silẹ.

Ọlọgbọn ni ika "Ewo." Sisẹ-ara-ẹni ... iwa ti Jesu Kristi fi lelẹ fun wa bi apẹrẹ.

*Translated By*

ADEYINKA AJAGBE-ỌLA

## Ẹ DIDE, Ẹ DIDE, Ẹ DIDE, SARI ...

Lati ọwọ KEKERE AWO.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*,

Mo bẹrẹ f'oji,

Ipade Igbimọ Aṣofin mbẹ loni ni Gbagan ile Sẹkiteriati, a yin si wa leti fẹnrẹn wipe a... ẹniti ilu fi ṣe Aṣoju si Igbimọ Aṣofin boya nwọn tun sọ lu ọran owo-Ajulọ kanna, adura tiwa ni ki Ọlọrun gba ajo awọn ilu ki nwọn le bọ ... niuu ẹru lẹnkeji, eyiti nwọn nfẹ sọ wọn da ... ọdun yi.

Owo "Income Tax" yi ti Ijọba nfẹ mu enia ... san o jẹ owo afi agbara gba, dujudaju ki yio ... omnira kan fun awọn ara ilẹ yi mọ, gẹgẹbi ... ede enia dudu tabi ọmọ abo Ọba Dosunmu ... mọ wipe Ijọba Igẹsi fi ipa gba gẹgẹbi alagbara ... Ijọba Igẹsi lo da owo ẹru ṣiṣe duro nigba ... nwọn ri irufẹ inira ti o mbẹ ninu rẹ, nipa eyi o ... mu ki ilu di omnira ara wọn.

Ijọba Igẹsi yi si ni ẹniti Ọba Akitoye pe ... sihin lati wa pẹtusi ija on pẹlu Ọba Kọsọkọ, ... o si mu wọn duro nihin titi Ọba Dosunmu fi ... ilu le wọn lọwọ lati wa labẹsẹ Ijọba wọn ... didabo bo awọn ara ilu rẹ.

O ha tọ nisisiyi lati ri wipe irufẹ ofin bayi ... lati muwa si arin ilẹ yi? Bi o tilẹ jẹ wipe Ijọba ... nawo, ki a tilẹ wi bẹ, debi wipe a ko tilẹ mọ ... Ijọba nfẹ lati ma gba owo yi fun, ni iwọn igba ... jẹ wipe, ọda owo ko da Ijọba ti nwọn kosi fi idi ... tẹrun han awọn Aṣoju ti ilu yan si Kansulu ... idi ohun bayi li awọn fẹ fi mu ilu san owo ... ki awọn Aṣoju ilu si ri wipe ohun pataki li nwọn ... fẹ lati ma fi owo na ṣe nitotọ.

A sọ wipe a ko fẹ ki nwọn ṣe owo ẹru mọ ... dara nitotọ, ṣugbọn lai si ani-ani, kosi iyato ... owo ẹru ṣiṣe ati mimu ilu lati ma san owo ... lọdọdun, lai ni sababi kan pataki, bi o tilẹ jẹ ... Ijọba nwa owo lati na, ki awọn ara ilu ... gbangba ni gasikiya, a ko tanma wipe ṣiṣe ... lọwọ iru inawo bẹ fun Ijọba ko ni ṣe ohun ... fun awọn ilu, ṣugbọn eyi ko ri bẹ arara.

Ijọba ko ṣai mọ iru ipo wo ni ilu wa nipa ... ṣiṣe ati nipa tita rira fun awọn oyinbo oniṣowo ... fun awọn enia dudu ti o nṣowo pẹlu, gẹgẹbi ... wa fun wọn si, bi nwọn ko tilẹ mọ, o dara ... nwọn ṣe itọsẹ yi lọdọ oyinbo Aṣoju awọn oniṣowo ... ni Igbimọ.

Kosi ohun ti awa le sọ nipa eyi ti o le jọ Ijọba loju, aiyafi ki nwọn ṣe bayi.

Ijọba tilẹ nwi, nwọn nsọ wipe awọn yio ma yọ ere kuro ninu iṣẹ tabi owo ti olukuluku ba nṣe lododun lẹhin ti nwọn ba ti mọ iru bukata ti oluwarẹ ngbọ ninu ilu rẹ, nwọn si so gẹgẹbi iye ti awọn yio yọ kuro lori iye kan lati ṣile mẹfa lori ọgbọn Pọnun titi de Pọnun mẹwa lori Ẹgbẹrun Pọnun, eyi ni eto pataki ti nwọn ṣe fun gbigba owo na, nda o, eyiti koi ti ye wa to nibẹ ni wipe, ti nwọn ba gba iye kan lowo enia dudu gẹgẹbi iṣiro ti nwọn ba ṣe, ti o ba tun di lodun keji iṣiro omiran ti nwọn yio tun ṣe ni, tabi lori iṣiro iye ti nwọn ti ṣe lakoko ti nwọn yio duro le lori? Eyiti kosi ye wa nibẹ ni iyẹn kosi wu wa lati bere, ṣugbọn o yẹ ki a kan sọ gẹgẹ ni mira pataki ti a ri wipe o kan inira ti o mbẹ lori owo na.

Nitoripe ti o ba jẹ wipe ero wọn ni lati fi oke le iye ti nwọn ti bu fun ẹnikan ri, lai bikita fun ṣiṣiro ere ti oluwarẹ jẹ lodun to kọja mo, njẹ bi oluwarẹ ko ba ri ere jẹ to ti odun to kọja, boya nwọn le sọ wipe oluwarẹ le ri asiki julọ ni igba miran awọn ko bikira lati mọ o, bi o ba jẹ bẹ, a ba bere iṣẹ wo lo jẹ pataki ti enia le ma ṣe tabi ọja wo lo nlọ daradara nsisiyi ti enia le ma ta ti asiki rẹ yio fi ma yọ, inulẹ ero yi lo pẹlu, li a fi nke fun Ijọba pe ati owo-ori ati owo ẹsẹ kosi eyiti o dara fun ilẹ yi ataara, bukata ti ara ilẹ yi nṣe mpa owo wiwọle si apo Ijọba, a le fi ogun rẹ gbari wipe ṣaṣa li ilu ti a le fi we e ilẹ yi ni gbogbo ilẹ enia dudu.

Nitorina a bẹ Ijọba gidigidi tọwọtọwọ lati fi gbigba owo na si ero ti o kuna fun awọn ara ilu, bi a tilẹ ni nwọn tiṣe ni ofin ni Igbimọ ni ọjọ 24 August 1927, a ni bi a tilẹ ni ero pataki ni nwọn nilẹ lati ma gba owo na fun, eyiti o ṣokunkun fun awọn ara ilu, lai fi ṣe bi o fẹ bi o ko fẹ tulasi, gẹgẹbi iwa alagbara, ikunsinu ti pọ pupọ julọ lori owo yi laria ilu, o si jẹ ohun igbona ara fun wọn debi ti a fi le sọ wipe boya ẹnikan lo nba wọn ṣe apamupamu wipe nwọn ko gbodọ san owo kan, kosi ẹniti ko mọ bi inira ti wa fun on si li aseko yi, nipa atijẹ-atimu, ati nipa gbigba owo yi lagbara lowọ awọn ara ilu, ole mu wọn lokan balẹ gẹgẹbi a ti ro, wipe njẹ bi o ba tun ṣe si die Ijọba ki yio tun wa ofin titun kan gbe ju silẹ, ki nwọn si ma fi agbara won lo ofin na, yala o tilẹ dara bi ko tilẹ dara fun ilu.

A tun fi gbogbo ọrọ na le ẹnyin Aṣoju ilu lọwọ (mọ. Jonsi ati Kọlkriki) lọwọ, a si tun ke si ẹnyin oyinbo Aṣoju awọn onisowo, oyinbo Aṣoju Bank, oyinbo Aṣoju Ọlọkọ-ilẹ (The General Manager of the Railway) ati oyinbo Aṣoju awọn Ọlọkọ-omi (The Member for Shipping) ki ẹ jẹki ọrọ ofin owo Ajulọ (Income Tax) yẹ Ijọba gidigidi, okun bata to ja ni, ẹsọ lo gba.

Emi ni tiyin nitoto,

**KEKERE AWO.**

## O ṢEUN, ṢEUN, IJẸBU ỌMỌ ALARẸ, O DABI ENIA MẸFA.

Okiki lati Ijẹbu Ifẹ fẹrẹ di wa leti nipa inawo ti ọrẹ wa D. A. Adeniga, Onisọna aṣọ ti 25, Layẹni Street, ṣe ni ilu rẹ.

A gbọ wipe ọrẹ wa lo si ilu rẹ lẹhin ti girigiri iṣẹ odun ti rọlẹ ni *January* lati lọ ṣi ile ti o ti nkọ ti Ọlọrun si ba pari.

A ba gun ẹsẹ ninu iya ọrẹ wa ko kọsẹ fun bi inu re ti dun to, nitoripe owo to pari ile na nlọ bi ọdunrun pọnwun.

Ẹsẹ ko gbeji ni ọjọ na jẹ; ẹgbẹ npe ẹgbẹ ranṣẹ, ọrẹ, ojulumo lati Eko, Abẹokuta, Ijẹbu-Ode, Rẹmo, Ikorodu; ọkọ nkọlu ọkọ, moto nkọlu rawọn, iyawo ko jẹ ki a mọ iyale, ọmọ ile ko jẹ ki a mọ alejo, ohun jijẹ ko jẹ ki a mọ ohun mimu, gbogbo rẹ nṣe yungba.

A ki ọrẹ wa o ku abọ, o ku inawo, o ku ori rere ki Ọlọrun ko jẹ ki o lo ile na pẹlu ẹmi ati alafia ara ki o si fi le ọmọ lọwọ,—*Amin.*


## INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA.



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi" jẹ ojulowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ṣẹṣẹ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Ṣango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ

Oriṣi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

**Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.**

**Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maṣe gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.**

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, FEBRUARY 18. 1928.

## "ỌNI ALAPAKO" WỌ'LU, Ẹ PARADA!

Irohin kan to bẹ si'ẹ nilu ninu ọsẹ yi ni ti fifẹ ti a gbọ pe awọn enia diẹ nfẹ ọmọ wọn ku; ni igba lailai ni awọn agbagba nsọ pe bi awọn mosondoki enia kan ba fẹ ji ọmọ-ọlọmọ lọ ta, nwọn a kan pako pọ bi ọni, ninu eyiti nwọn nwọ, nwọn a si ti ilu okere miran wa si Eko, nipa kikosi apako ti nwọn ti kan wonyi, n..n a si fi wẹ wa si eti ebute Eko, ..pa so ọmọkọmọ ti ọwọ awọn eniakenia wọnyi ba tẹ, lọgan ni nwọn yio ti ko lẹsẹ mejeji ti nwọn yio si mu wọ inu iho apako ti nwọn wa ninu rẹ, ..gafa, o di ki nwọn mu lọ si isalẹ omi titi nwọn yio fi luwẹ lọ si ilu ibomiran pẹlu ọmọ ti nwọn ba gbe na, o buṣe niyẹn, irufẹ ọmọ ti ọwọ won ..a tẹ bẹ di tita lọ si ọna jijin rere.

Ni iwọn ọdun pupọ sẹhin ni a tun gbọ ti sisọnu ti ọmọ nsọnu larin igboro ilẹ yi, nigbati Ijọba dide si ọran na, o re iiẹ, ṣugbọn nisisiyi si ni a tun ngbọ pe awọn kan tun bẹrẹ aṣakaṣa na; gbogbo enia le jẹri si otitọ yi pe ni gbogbo ilu ti o mbẹ ni Nigeria, a ko ri ọkan tabi meji ti o le jọ ilu Eko ni oriṣiriṣi anfani, ẹ jẹ ki a mu apẹrẹ kan; bi awọn ọmọ wẹwẹ fẹ ṣere, papa ni igba oṣupa lati agogo mẹjọ alẹ titi di agogo mejila oru, ti nwọn ko ba pariwo ju tabi ki nwọn ma sọ'ko, ndao ko si ẹnikẹni ti yio fi nkan ṣe wọn, ayan ko ni yan wọn, bẹni era ko ni ra wọn, bi enia ba si fẹ rin arin-mọju ni, ti ko ba ti jẹ pe o rin irin ọsọlẹ lẹsẹ, agbedọ, ki o ma rin ki o ma yan ni, irufẹ aṣa bayi ha wa ninu pupọ ilu omiran bi? Ko daju; awa papa ti lọ si awọn ilu diẹ bi Onitsha, Lọkọja, Idah, Asaba ati bẹbẹ lọ ri, a si ri pe bi o ba ti di nkan bi iwọn agogo mẹwa alẹ, kere ni gbogbo ode yio da, ti ọwọ yio pa ti ẹsẹ yio si pa pẹlu.

Eṣu ṣe ẹnikan ni ilu awọn Ajẹnia, ki rẹ ta felefele lẹ' in agogo mejo alẹ, oluwarẹ ko ba ni ba ori ara rẹ ni ikoko nigbati awọn ọmọ ogun ba ti fi se "kọlọ tan, ti o ba ri aja ..wulọ ki o ma ki.

Igbagbọ wa ni pe fifun ti Eko fun gadi bi ẹja panu bayi, ti oriṣiriṣi iluk kun inu rẹ fọ, ni o mu aṣa wiwa ọmọ nilu wa, ẹru jẹjẹ ko ha de si awọn gbogbo lati bẹrẹ si mu ọmọ wọn tete bi adiẹ lẹhin agbarọ alẹ, papa ninu ako yi ti awọn Musulumi npete ati mu A laipẹ lọ mo titi.

A ke si Ijọba, papa awọn Ọga Ọpa Ọba nwọn da awọn "Gidigaro" wọn si ilu ki bẹrẹ si fi imu finlẹ mọ irufẹ awọn abe enia ti nwọn bẹrẹ si aṣa gbọmọ-gbọmọ yi lẹnu ọjọ diẹ yi ni a gbọ pe awọn obi ka fe ọmọkọnrin meji ninu awọn ọmọ wọn ku eyiti a gbọ ni a nsọ yi, bẹ boya awọn ọmọ miran ti a fẹku bẹ tunwa; gbigba ti Eko gba t'ẹru t'ọmọ, t'onile t'alejo lo mu ki ki orin yi di owe lẹnu awọn elomiran pe

"Ma rin, ma yan,
Ma ṣanpa, ma ṣansẹ,
Ma jalankato."

O dọwọ nyin o, ẹnyin Kiniun Eko.

---

### OLUSAKIN'S COLUMN.

#### Dramatic Entertainment

A Dramatic Entertainment arranged by the memb of the Youngmen Friendly Society of the United Afric Methodist Church, Ebute Mẹta, of "Alagbato ko mọ ọmọ" ati "Ako tirẹ wa ba t'ẹni" interspersed with so recitations and dialogue was staged in the United Afric Church, Jebba Street, Ebute Mẹta, on Friday, the 1 February, 1928, at 8.30 p.m., under the Chairmanship S. A. Shogbẹsan, Esq., supported by Dr. J. C. Vaugha Revs. J. F. Ogunko, E. Ayo Salu, D. A. Bababunmi J. O. Shọpẹkan, J. A. Oshodi, Esq., D. Ayodele Bright, Es J. B. Coker, Esq., O. Eṣuronbi-Arc, Esq., D. A. Ogunb Esq., E. A. Thomas, Esq., D. T. Abraham, Esq., J. Oshoba, Esq., M. O. A. Joseph, Esq., and S. S. Ajose, E

The Church was full to overflowing, and the Enter ment given by some of the actors and actresses w interesting; special mention may be made of Miss Ag Joseph, "as Angel" Master F. A. Beckley as "Tiger" with J. A. Adeoye who killed the "Tiger" with a "toy revolv when the "Tiger wanted to jump at him. [laughte and Messrs. C. A. Akipelu and E. A. Macaulay who ac their parts as "Pharisee" and the "Publican" respecti in a creditable manner.

The amount realised was in the neighbourhood of something reasonable.

We congratulate the Pastor-in-charge of U.A.M. Church, Rev J. O Shopekan, Mr Charles Akipelu Managing Director and Mr. J. O. Coker, the Secretary, for the success of the evening

### Arrivals

The Right Rev Bishop A. W. and Mrs. Howells arrived Lagos from Eastern Division, by the *R.M.S. Abinsi*, on Thursday the 9th instant.

---

Mr. I. T. Palmer of Sapele has been appointed an Unofficial member of the Legislative Council of Nigeria. (for Sapele and Warri Provinces ?)

Mr. Palmer arrived in town last Thursday the 9th instant, for the Council meeting taking place today.

### Departures

Major Walter Elliott, M.P., Captain G. M Garro-Jones, M.P., and Colonel Sir Harry Moorhouse, C.M.G., D.S.O., were among the passengers by the *R.M.M.S. Appam*, which sailed this port for Liverpool last Friday, the 10th February, 1928. We wish them bon Voyage Home.

---

The Right Rev. Bishop A. W. Howells, left Lagos for Abeokuta, on Monday the 13th instant, on a short visit to his father

### Birth

Congratulations to Mr. & Mrs. J. A. Haastrup of 45, Aroloya Street, Lagos—the gift of a daughter, on Wednesday, the 8th February, 1928. We understand that both mother and child are doing well.

### Resumption of Duty.

Mr. E. O. Macaulay of the Nigerian Railway Traffic Audit, Ebute Meta, who has been on a month's leave, has resumed his duties from the 13th instant.

### Promotion.

Mr. Jeariogbe Tubi, 1st Class Clerk, Administrator's Office, Lagos, has been promoted to the rank of an Assistant Chief Clerk, with effect from the 1st October, 1927. Congrat

### Income Tax.

£45,000,000 loss in Revenue necessitates the people in Greenock to pay an Income Tax of 2s. 6d. per head, but here in Lagos a surplus of over £6,000,000 in Revenue compels the Government to demand from the people payment of an uncalled for Income Tax. How generous and considerate is our local Government ?

Below is the article reproduced fro the *Daily Mirror* :—

### 2s 6d in £ Income Tax

SIR GODFREY COLLINS EXPLAINS HOW IT COULD BE DONE.

Half a crown income tax was a practicable proposal, declared Sir Godfrey Collins the Liberia M.P., addressing a meeting at Greenock.

The loss in revenue to the Treasury would be about £45,000,000, in the first year and about £75,000,000 in a full year. The loss could be faced only by making corresponding cuts in expenditure.

Imperial Preference and the Empire Marketing Board, which cost the taxpayer about £5,250,000 each year, could be abolished without hurting any of their own people.

The best sugar subsidy, which losts about £5,500,000 and brought no direct or lasting return to the nation, should be discontinued.

Thirty million pounds could be saved if the size of the defensive force was adjusted so that the cost would not be greater per head of the population than in 1914.—*Daily Mirror*, 12/1/28.

OLUSAKIN

---

## OLOTỌ-ILU LI OṢIKA-ILU.

---

### LATI ỌWỌ KEKERE-AWO.

---

Si Oniwe-irohin " Eko Akete,"

Mo bẹrẹ foji o,

Bi ema ba nwo irufẹ iwa awọn apakan ni arin ilẹ yi, awọn ẹniti nwọn nro wipe ọna ti awọn mu ṣiṣe ilu wọn gba jẹ ọna suna, yio mu ki a ṣe ewe asuru jẹ, yio mu ki ọrọ ilu su ni patapata lati sọ, ni idakeji ẹwẹ ti a ba tun ranti wipe bi a ba ni ki a ṣe bayi yio jẹ ohun ti o le mu eri buruku ba ilu lọjọ omiran.

Ki iṣe aseko ti awa ero isisiyi li a nsọrọ le lori, awọn iṣi kan tun mbọ ti nwọn yio tun ma sa ipa lati tẹle ọna ti a ba ṣan silẹ de wọn, ọna ti nwọn ba ba nilẹ yala li ọna ire tabi li ọna ibi ohun ti nwọn yio tẹle, njẹ ti o ba tọ nisisiyi lati fi gbogbo aseko wa ṣe arede, titi awa yio fi papoda ti awọn ẹlomiran ti nwon tun mbọ dandan lẹhin yio si tun bẹrẹ lati ṣe eyiti a ba ṣe ku silẹ.

Awa kosi ninu awọn ẹniti a nsọrọ le lori, iduro ti awa nisisiyi ni wipe *a gode Allah*, a ba Ọlọrun duro, a nwoye, bi awọn ara ilẹ yi ti ma ṣe igbesi aiye won si lati fi to ilu wọn gẹgebi o ti tọ, de awọn iran wọn ti o tun mbọ nigbati awọn ero isisiyi ba ti ṣe ti wọn pari.

Tẹlẹtẹlẹ ri awọn kan li a ri ti nwọn ti nṣe ilu Eko yi ni jẹlẹnkẹ, awọn ẹniti a kole ma daruko wọn loru, nitori ki iṣe ohun ti ọpọlọpọ awọn ẹniti o mbẹ ni sa wọn ko mọ, bẹni ki iṣe ohun ti awọn ọpọlọpọ ọmọ ilu ko ti ṣai gbọ itan wọn lẹnu awọn agbalagba.

Nigbati awọn ẹniti a nwi yi mbẹ larin ilu Eko yi, ti nwon koi ti tẹri gba aṣọ tan, ki iṣe bi ilu ti wa ni rudurudu yi li o mbẹ.

Awọn oyinbo ti awọn apakan lọ'se mọ julọ lati ma ṣe bi motomoto, ko ṣai si nigbana, awọn oyinbo mbẹ lopọlọpọ gẹgebi nwọn ti mbẹ ni isisiyi, ọgbon ati lakayi ti awọn ti sa atijọ ni, na li awọn ti aiye ti a wa yi papa na ni, gbogbo wọn ni nwọn si mọ iyi awọn ara ilu, gidigici julọ.

A nsọ wipe ọtẹ ti nwọn ti nṣe ri ni lailai, ko to ti igba yi, ẹniti o ba sọ bẹ, iro funfun ni oluwarẹ pa, ọtẹ ti o nwọn nṣe ni ilu yi ri, ki iṣe ọtẹ ibiti

ida nję ni ida nwo, bi ęnikan ba sọ wipe on lowo, nwọn ko ri irufę on ti, ti o ba ṣạtojudi si awọn agba ilu, lai sọ ti awọn ojoye ilu, oluwarę mọ wipe on gbe'rọ, nwọn yio jęki awọn oyinbo da sẹria fun wọn, awọn oyinbo ti a wi tẹnyi, nwọn ko ję ję ka yo tan, ki nwọn fi ibiti enia gbe pọju si sılę, ki nwọn duro sẹhin awọn bi melo kan, ti nwọn ba şe bę, nwọn ti mọ wipe laifi li awọn şe si ilu tabi awọn ojoye, nwọn si nsa fun laifi ilu pupọ, bęni awọn ilu papa si nsa lati şe aşemaşe kan si wọn, bayi li nwọn nşe jẹlęnkę ti gbogbo ilu si nlo letoleto ti kosi si agbodo alugi li ti awọn oran ti nwọn nfi apa janu kiri loni wipe awọn li awọn ndun ni ilu, ohun ti awọn ba şe li abę ge

Irufę şişe bayi kę, lati igbati gbogbo rudurudu ti delę, kosi rere kan ti o şe, bokanran eyi, idamu on ipaiya lo nko ba wọn.

Kini ipaiya on idamu? Ọpọlọpọ ęlomiran ti o ni owo lati fi şe gęgębi o ti tọ si arin ilu, nwọn ko lero lati şe bayi, bi ọran kan ba ję mọ ọran ti o le mu ęnikan ninu wọn şubu, ikekiye ti apá wọn ba ka ti nwọn o ba fi şe anfani fun arawọn, nwọn a na fa, agbarewa-agbarebọ ofifo ẹjọ keji ọja Ẹjinrin lo ma bo si, ibiti o gbe towọ bo ti o gbe mu owo yi, a gbe fun u şọ tabi owo ti oluwarę papa ni lọwọ fun aiare, dajudaju eyi ni di gbese si i lorun, ti o ba si di gbese tan bayi, ipaiya ni lati de, bi ęlowo ba si mbere owo rę, idamu ibiti on yio ti ri owo san ni lati ba a, o di wipe ki oluwarę gbe aisun ati aiwo dani, li ọna ti oluwarę ma gba ti yio fi ri owo ti o bana pada si ipo rę, ti o ba ję wipe owo olowo ni oluwarę tọwọ bọ.

Şugbọn ti o ba ję owo ti ararę ni oni lagbaja lo mu owo wa, ọla tanmẹdun lo mu owo wa, ki a fi dilę bi oluwarę ba nmu bę lojojumọ, ti o ba di ọjọ kan owo na yio sọ fun olowo rę wipe ki o rọra mu on, ki on ma tan nibę, alalikuwa gbogbo ọna ti a nna owo yi si okibo ni orukọ ti o nję.

A ti ri ọpọlọpọ enia ni ilę yi ti o ję wipe kosi suna meji ti o dara ki a fun wọn, bikoşe o ri owo olowo fi ọkan balę, nipa fifi owo ba ilu ije lati fi ję olori tabi Gawa Samọnsagudu sina ote, irufę awọn ęni bayi ọkan wọn nję wọn lęri wipe kosi anfani ti awọn ri laduru ęgdileję owo olowo ti nwọn kan na danu lasan-lasan, eyiti o nmu ọpọlọpọ wọn şe hilahilo nisisiyi ani ti nwọn nke abamọ wipe kosi rere kan ti awọn ri latari gbogbo owo ti awọn na lati bi ęnikan şubu; irufę awọn ęni wọnyi, kosi ohun ti a ko sọfun wọn tan wipe ki nwọn lo fi ẹdọ lori orẹro, nwọn ha gba itọ wa dami bayi, nwọn ko gbọ ohun ti araiye nwi arara, loni nkọ ęnyin arabi, bi aşa awọn alaşa, nwọn ni ọjọ lo ma tumọ asunde, ko ha ri bę fun wọn ni ikęhin? Ęniti o ba si ni ko ri bę fun on, ki oluwarę dahun ki a gbọ ni igbana li ao to mu gege wọn ti ao fi, tọka wipe iwọ lagbaja, ati iwọ

lakaşegbe, bayi-bayi nkọ kitigbe bi aşa awọn onilę, nigbana li ęnyin ilu ę ba ri kisa.

Ki a tun wa fi abọ ba gbolohun ti a fi bęrę wa pe Oloto-ilu li oş ka-ilu.

Anu dię lo şe wa wipe gęgębi ọrọ ti nlọ si ti awọn onimutumute si nşe gęgębi nwọn ti fę, nkọ wa li ęmimu tun ọran ilu yi.

A tilę gbọ ti igba kan ri ti nwọn nso wipe apakan lo nşe atilęhin fun Ijọba wipe ki nwọn awọn ara Eko lati san owo-omi, ti gbogbo awọn Imale si nba arawọn şe akatakiti wipe awọn Kiriyo lo nfi wọn nitikuti lati da imọ wọn ru, ti nwọn ja ija fun bi iwọn ọdun marun titi Ọlọrun fi pętu si.

Ọran yi lo mu rudurudu wa fun awọn Imale Eko, titi di ọjọ oni ti a nsọrọ yi tọbę ti Ęşu fi [illegible] wọn lagbara.

Nigbati a ni ọran omi ti a nwi yi delę, awọn Kiriyo papa ko parọ mọ, titi Ijọba fi [illegible] awọn ara ilu lagbara lati ma sanwo fun omi. [illegible] o ba ję wipe, awọn apakan gba ęiyę si awọn omiran ani ti o ba ję wipe awọn ijọ kan lo nba Ijọba pete omi yi lati mu awọn ara ilu sanwo, ani ti o ba ję wipe awọn apakan lo kọkọ lo sanwo tiwọn fun Ijọba, ki awọn ara ilu file mọ wipe munafiki li awọn şe siwọn, awọn li awọn pe ole wa ja tan, ti awọn tun pe olo o pe ki o wa sọ, ani ti o ba ję wipe awọn ti awọn şe ileri fun awọn ara ilu wipe bokanran ki awọn san owo omi lo ti Ijọba nfę mu wa yi, ki nwọn di wọn ki nwọn gbe okuta le wọn laiya ki nwọn lọ ju wọn sinu omi Lęhingbęti ani ti o ba ję wipe ti o ba wipe awọn li awọn şe ileri fun gbogbo ara ilu wipe ki nwọn ma wa da owo lati fi gbogun ti ọran owo-omi, ti gbogbo ilu si fi igbona ara dami na, ani ti o ba ję wipe awọn lo tun pada, ti nwọn tun nda awọn ara ibi l'Eko lati ma san şile kọkan fun owo-omi, nitoripe awọn rinirin ọran na ti ko şe şe, ti nwọn ko si jęwọ fun wọn wipe, nwọn kilo fun wọn wipe bi nwọn ko ba dẹhin lẹhin akatakiti nwọn nşe si owo-omi, nwọn a kan idin ninu iyo werewere, ti nwọn si wa fi ęhin awọn ęniti o da owo sidi ọran yi da'gun, ki a wi bere wipe tani ęniti o ję kayo tan nisisiyi ti o ba awọn Munis ba ki ifun on ni iwe omi sisan ni *June* ati ni *December* ani lęnmeji larin ọdun kan.

Ęniti o ba ni eyiti a wi yi beko, a bę oluwarę ki o jọwọ ki o ye ki o da wa lohun, ki a ba le mọ u lorę, boya nipa bę awa na yio di ọrę Munisipa, nwọn ko ni gba owo omi lọwọ wa mọ, tabi oluwarę ko ni jęki a sanwo omi mọ fun awọn Munisipa.

Gbogbo awọn ęniti o nja nigbana wipe bi Ijọba tişe fę mu owo ilu sanwo fun omi, ko wi arara, ni iwọn igbati o ję wipe orugbę omi lo gbę ilu, bi orugbę omi tilę ngbę wọn, awọn

omi 'digbolokun ti awọn nmu lọjọ ti o ti pẹ, li awọn apakan ara ilẹ yi tabi awọn ẹniti o nleri leka nigbana wipe awọn ko ni sanwo omi ni ilẹ yi lailai sọ di ọta, tabi oşika ilu, tabi ẹniti o nda ilu ru, ti o si nta kanrangba si Ijọba pẹlu.

Tani ẹniti o le sọ wipe gbogbo wahala arumọjẹ lati fi gba ilu lowo jẹ, lẹhin ti nwọn ti ki iwọn nilọ wipe bi nwọn ko ba so agbejẹ mọdi nwọn a ri ohun ti nwọn ko tanma, ko jẹ ohun aimọyanlori fun on.

Olowo nsanwo omi talika si nsan pẹlu, awọn ẹniti o tilẹ fi gbogbo ilu ra ile ra ọna, ani ti nwọn fi gbogbo ode kọ ile kasẹ si lo tilẹ njẹ igbadun owo yi loni, ti a ko gbọdọ sọ wipe nwọn njẹ irora rẹ.

Nigbati ọran owo-ori tabi owo Saka Ọdọdun, lati ma yan fun Ijọba, mbọ wa yi, eyiyi ni *(Income Tax)* ki lo si tọ ki nwọn şe o? Şe o tọ wipa ki gbogbo ilu panupọ fun ọran ẹhin ọla, lai loiya, li ona irẹlẹ, ki nwọn si lọ ba Ijọba sọrọ bi o ti tọ ati bi o ti ye, agbẹdọ nwọn ko jẹ şe bẹ, ori inu ti ba ti ode jẹ, kini ki a ti gbọ wipe awa ni a tun wa nsọ wipe ofin ti Ijọba nfẹ mu wa ko dara, awon ko ni şe bẹ lai, nwọn nkorira lagbaja, nwọn nkorira lakaşegbe iyẹn badi. Mo rc wipe awọn apakan, lo gbe wahala ọran yi dani lai boju wo ẹhin, sori ọran owo Tax yi, lati gba awọn ara ilu silẹ, lọwọ wahala ati lowọ iponju ani kuro ninu ẹru, eyiti Ijọba Igesi nfẹ sọ awọn ara ilu da ninu ọdun yi, awọn ẹniti o si gbe ẹru ọran yi lori nisisiyi kọ ni a gbọ wipe awọn omiran tun nşe mutumutẹ abẹlẹ si wipe, nwọn nkọ awọn ara ilu lati di karewa si ọran owo yi, bi irufẹ awọn ni bẹ ba tilẹ nro wipe ọna ti o dara li awọn ntẹle nipa didi rikişi awon ẹniti o nja fun rere ilu, nwọn ha ro wipe, o le jẹ ohun ikosẹ fun awọn ọmọ wọn, lẹhin ti awọn ba ti kuro ninn lala ati fitinati aiye tiwọn?

Ẹnyin ilu, ẹ ku agba, ẹ ku wahala ilu nyin, ẹniti o nşe ire, ki o ma şe ire, ẹniti o si nşika ki o ma şika, ati ire ati ika, kosi eyiti o ngbe nibẹ.

## ẸKU IPAMỌ!

Titi ọjọ Alaruba tabi ki iwe wa to tun jade, awọn Musulumi wa jio ti bẹrẹ si ki arawọn ku "ORUNGBẸ"! ti awẹ. Boya gẹgẹbi a ti gbọ lẹnu wọn si, wipe ọjọ Atalata li ọjọ ti oşu pe ti nwọn yio si ki Irun (Aşamu) awọn Imale afi apa ẹlẹdẹ jẹ sari le sọ wipe ọjọ Monday Ọtunla tabi lọjọ Alamisi ọjọ mẹfa li awọn yio mu Awẹ tiwọn. Nitori kini a şe sọ bayi, gbogbo nkan lo nyi laseko Olowo, nitori ki Ọba ma waja: Şugbọn nwọn gbagbe wipe Ọlọrun ti awọn nsin I, ki işe Olowo aiye, eyiti awọn omiran sin ni lọlọyi ti nwọn fi tapa si suna ti Ọlọrun, o nye nyin o.

A şe adura fun gbogbo nyin ọkunrin ati obinrin, onile ati alejo, agba ati ọmọde, ki Ọlọrun jẹki o 'ba ẹmi, ki O si fi ohun ti ẹ ọ fi şika awẹ na fun nyin—Amin.

Emi ni tiyin nitotọ,

KEKERE AWO.

---

## KINI NJẸ ỌDUN GBẸIYẸFO.

[ Lati ọwọ Ọmọ Awo ]

Si Oniwe Irohin *Eko Akete.*

Ko dede ti a fi şa bere ọrọ oke yi, a ma ngbọ ti ọpọlọpọ awon enia ma npe ọdun kan ni ọdun Gbẹiyẹfo eyi ti awa mọ ni *Leap year*, awọn enia a ma nsọ fun ni pe ọdun *Leap year* gẹgẹ bi ọdun 1928 tabi gbogbo ọdun ti o ba jẹ *Leap year* ki nşe ọdun rere ati pe iku si le pọ ninu rẹ, awawi l'awa ri eyi si ati pe isọkusọ lo si jasi, njẹ ẹnyin Onibuku ninu iwe wo ninu Bibile li a gbe kọ ni pe ọdun yi ki nşe ọdun rere, ọdun wo lo ha wa ti ki nşe ọdun rere, laisi ani ani ohunkohun ti enia ba fi ẹnu ararẹ fa lo ma ri, ẹnikan nşe mi ko si nibẹ; njẹ mo fẹ bere lọwọ awan onisọkusọ wọnyi pe ọdun 1918 ha nşe ọdun *Leap year* ti Ajakalẹ Arun fẹ run gbogbo Aiye tan, tabi ọdun 1923 ha nşe ọdun *Leap year* ti awọn ọdọ ti o şeşẹ gbe iyawo tan nigbana ku lọ bẹrẹrẹ, Oluwa jẹ ki iru iku bẹ ma jinna si rawọn, ẹ o ri pe ko si ọdun ti nkan ko le ba enia, ohunkohun ti o ba si ba enia, ẹ jẹ ka gba pẹlu idupẹ, ẹ ye fi isọkusọ nyin ja awọn ẹni to fẹ gbe iyawo l'àyá, Oluwa ko ni jẹ ki wọn ri ikọsẹ, bi isọkusọ ti pọ laiye to, awọn enia miran nsọ fun ẹlẹgbẹ ti o npalẹmọ ati gbe iyawo pe, aşọ ti a npe ni *Gray* ko dara lati fi gbe iyawo ati aşọ bi ***Black over trousering***, ẹnyin gbajumọ ninu aşọ kini tun dara lati fi gbe iyawo ti ẹwọ ***Morning Coat*** ba ti yọ ju awọn aşọ wọnyi lọ, a si bere pe kini gbajuta na ri ki o to ni awọn aşọ nwọnyi ko dara, ko le sọ nkankan mọ ju pe, on sọ ti on to, irọ gba l'aiye yi niyẹn, ko ba dara pupọ bi Burọda na ba kuku natan fun wa pe on ko ni kudi lọwọ ka kuku mọ arun ti o nbaja nwo, a tun wa bi ọdẹlẹsirin yi pe, iru aşọ wo ni iwọ rope o tọ suna lati wọ fi gbe iyawo, o ni aşọ kan ti nwọn npe ni Santọnu ni o tọ suna, ẹ ko wa ri arun ti o nşe Ọgbẹni yi o, ninu awọn aşọ to o ni ko tọ suna pẹlu aşọ ti o ni o tọ suna nwọnyi on, ewo lo ha dara wayi o, bi a ko tilẹ sọrọ kan mọ, mọmọ ti mọ iyẹn. Eko wa ri gbangba pe, ẹnu wa yi la fi nfa nkankinkan wa si ori ara wa, awọn ẹlomiran a ma sọ pe ọjọ kan lo da lati gbe iyawo, ọjọ kan ko dara, ninu gbogbo Ọjọ ti Oluwa da ewo ni ko dara ninu rẹ, tabi iwọ to ni ọjọ kan ko dara, nijọwọ lo ti ọdọ Ọlọrun bọ wa, ti o si sọ fun ọ pe ninu gbogbo ọjọ ti on da, ọjọ kan lo tọ suna, ikan

ni ko tọ suna, tabi ninu iwe wo la le ri ninu Bibeli pe ijọ kan ni Oluwa ya sọtọ lati gbe iyawo, a sa mọ pe Jesu papa lọ si ibi iyawo ri nigba Aiye rẹ, tabi inu wa yio si dun bi Imale kan ba le sọ fun wa pe, ọjọ kan ni Mọmọdu ya si ọtọ fun ọjọ igbeyawo ati idi ohun ti awọn ọjọ iyoku ko ṣe dara, ẹnyin Onibuku ẹ o jẹri si pe, daradara ni gbogbo Iṣẹ ti Ọlọrun ṣe titi fi di ọjọ kẹfa, ko to wa sinmi ni ọjọ keje.

Inu mi ati ti awọn ẹlẹgbẹ mi, ti yio ri si ọrọ wọnyi, yio dun pupọ, ti a ba le ri ẹni ti o ba le sọ fun wa idi ohun ti igbeyawo ko dara ni ọdun *Leap year*, awa ti ri pe Imale ko jẹ sọ bẹ, nitoripe ogun lọgo wọn lo ngbe iyawo lọdun yi, ekeji ẹwẹ, inu wa yio si tun dun bi a ba ri ẹni sọ fun wa, bi awọn ọjọ iyoku ko ṣe dara fun igbeyawo.

Lakotan, njẹ ko Oyinbo to ko àṣà Arede de Ilẹ. Eyi ti pupọ enia fẹran lati ma gbe ni ọjọ *Tuesdays* ati *Thursdays*, njẹ awọn Baba nla wa ki nti ngbe iyawọ ni awọn ọjọ iyoku ti o si nṣe wọn lanfani ju ti akoko ti wa yi lọ. Ogo kọ la wọn kan ni ka wa ma fi owo sinu Iwe Arede gẹgẹ bi ati ka ninu iwe yi ijẹjọ, nigbati o jẹ pe awa ti joye ko ni mọ kọ, aṣa alasa ti gba wa lọkan ju ti wa lọ, ọran yan ko sinu aṣa kiko ẹwun ni, ohun ti o ba wun o ni kaluku lọkan rẹ ni si ṣe, ṣugbọn oran agbere yi, ku diẹ ko to, bi o si wo awọn ti nwọn ni awọn gbe arede, na. Bi o wa wọn o ko ni ri wọn, kini awa nja pata si wayi o ko si siṣe, wọn ṣe nkọ wa pe, a to da duro fun ara wa, niyẹn, nipa evi ti a ya bara si yi, ọrọ ko ni si so, ṣugbọn bi o ti jẹ pe a ko iyẹn wa lo ni, a duro nibi na.

Awọn agbala ba ma sọro kan pe ohun enia ni ohun Ọlọrun, bi o ti wun o ni yawo lo ma ṣe nkan rẹ, ko kan ẹnikankan ninu rẹ, ẹ ye ṣe ṣọbọ si ọrọ ọlọro, bẹni enia kan sọ nijọsi pe *December* ko dara lati gbe iyawo, bi nkankan ba ṣe aya tabi ọkọ gẹrẹ ti nwọn ba gbe iyawo tan wọn a ni awọn ti wi, ko gbọ ni, ọjọ igbeyawo ko kan ki iku ma de, asiko to onikaluku wa da, ẹnikan ko mọ, nitorina a bẹ nyin, ẹ ye ṣe ṣọbọ si ọro ọlọro, ẹran ta ara nyin tara ẹni laran. Ẹsọ ko to nyin o ẹnyin o ni isọknsọ, oni palapala, ẹni gbe ẹ si ni jẹ ki ẹni to ma gbe ko gbe.—Bi yio ti dara Oluwa lo mọ, ko si ẹni ti o mọ bi ọla yio ti ri, ẹ jẹ ki onikaluku ṣe bi o ti pinnu lọkan rẹ—ọkan ẹni on ni Alufa ẹni—O dọwọ nyin.

Emi ni tiyin nitotọ,

ỌMỌ AWO.

## THE IGBAJỌ UNION.

Anu ṣe wa pipọ ni igbati a ri Alaga Ẹka The Igbajọ Union to wa ni Eko, nihin, Francis Abiọdun Ọga awọn Onifere Ọlọpa, ni Obalende ni jọ ọsẹ to kọja yi ti nwọn mu ọfọ Ẹgbọn rẹ eni ti o ṣe alasi ni jọ Alamisi ti o kọja yi, *( Thursday 2nd February 1928 )* ni ọna Igbajọ de Ikirun, Joseph Famewo Abiọdun o jẹ alakikanju ninu Ẹgbẹ The Igbajo Union ti Igboro Igbajọ, o si ṣe iṣẹ ọpọlọpọ ninu wọn ni iwọn ọdun diẹ sẹhin gẹgẹ bi ati gbọ ti gbogbo rẹ awọn ọmọ Igbajọ ndaro rẹ. Nitorina a ki Francis Ọlaia Abiọdun o ku rọju, Hannah Falẹyẹ Abiọdun, Elizabeth Faumi Ladele ( nee Abiodun ) Dada Abiodun ẹku irọju Ẹgbọn nyin ki Ọlọrun mu ọjọ jina si ọjọ. Francis abẹ ọ mu suru, kio ṣe giri bi Ọkunrin lati tu Baba nyin ninu, ki Ọlọrun ko si jẹ ke gbẹhin gbogbo awọn obi nyin. The Idajọ Union ẹ ku ọfọ akọni ninu ẹgbẹ, ki Ọlọrun ko pese ọṣiṣẹ sinu ẹgbẹ nyin Amin.

A ki Alaga agba awọn Igbajọ Union ti o wa lebute Mẹtta o ku afojuba awọn Oloye, rẹ, akọwe agba Ben Ogunọla Ọmọnijo, ati Akọwe owo ( Finacial Secretary, ) John Salakọ Ojo, a gbọ wipe awọn mejeji yi lo lọ si Igbajọ Ilu wọn lọ gbe Iyawo ati wipe awọn ati awọn iyawo ni wọn jọ pe. Ẹnyin Oloye mejeji a ki nyin o ẹ ku inawo ile o, Iyawo abi ọkunrin abi obinrin. A gbọ, tabi a le wipe Phebe Ajayi Iya Ẹgbẹ Igbajọ Union tun ni Ọmọ Ẹgbẹ meji si, Iya-ẹgbẹ ẹ ku orire o, a gbo wipe o fẹ si nyin diẹ ni ọsẹ to kọja tobẹ tẹ ko fi le ba awọn ẹgbẹ nyin pe, ṣugbọn a tun gbọ wipe o ti rekọja nisisiyi ki ajinde ara ma jẹ o.

Olotu Eko Akete mo dupẹ fun aye tẹ gba mi yi o.

lati ọwọ Rio ni ti Enia Ọlọrun loluṣe.

## AṢEJU BABA AṢETẸ.

### AJỌSẸ ONITANA ṢE AṢEJU LORI ẸJỌ TI O JẸ KI ADMINISTRATOR PE, O SI TẸ SI I.

[ WOSIKA LATI ỌWỌ ATARI AJANAKU ]

Mo bẹrẹ f'oji

Ẹnikẹni ti o ba fẹ jẹ ogun buruku ni lati pitan buruku ni ọrọ ti a le sọ si ẹjọ aramu ti oloye Ajọsẹ Onitana pe ọpọ enia ti o pe l'ẹjọ pe on, gẹgẹ bi Oloye Onitana, lo ni ilẹ ti nwọn wa, pẹlu ilẹ ti ọpọlọpọ ẹlomiran wa pẹlu; ati lai dena pẹnu, pe, on, pẹlu Oloye Oniru, lo pala pọ.

Bi agidi tabi alaimọkan tabi aifinipeni, aif'enia p'enia, ti ara oko fi nsan bantẹ w'ọlu, lo jẹ ki Ajọsẹ pe ẹjọ ti o pe, eyiti o jẹbi rẹ ni Thursday alamisi ijẹta, awa ko mọ.

Bi enia ba jẹ alagidi ọkan ti o ba ri nkan dudu, o le mọmọ pe e ni funfun; bi ẹnikẹni ba si sọ fun un pe ohun funfun ni, ki nṣe nkan dudu, o le ja ajaku akata sori rẹ; bi alai mọkan ba si ṣeşi pe ohun dudu ni funfun, ti o ba ri ẹni kilọ fun un, ti go ba nṣe aja ti o ba ma sọnu ti ki ngbo ofe, yio gba; bi bẹko, bi o ṣe ara Ibadan ni, yio wipe on nikan lo ni gbogbo Ikorodu.

Wipe Ajọsẹ Onitana ba Oloye Aromirẹ tan, tabitabi ko si ninu eyini; ṣugbọn pe Oloye Onitana wa ninu awọn Idẹjọ to ni ilẹ, irọ patapata, irọ funfun gbo.

Oloye Aromirẹ Ẹrinwa ni orişa pupọ ti o nbọ, o si fi Arẹmọ obinrin rẹ jẹ Erelu lati ma bọ orişa nwọnyi. Nigbati o ṣe Erelu ku, Mẹku ọmọ Aromirẹ kanna ti o jẹ obinrin si nbọ orişa yi. Şugbon nigba aiye Erelu, gele funfun lo nta m'ori bọ orişa, lẹhin iku rẹ Mẹku wipe o ı ko le we gele nitoripe on ki nşe obinrin. Aromirẹ sa jẹ alagbara ati oloye pataki pupọ lakoko yi, nitorina o fun Mẹku ni anfani lati ma de fila funfun dipo gele funfun, şugbon fila funfun rẹ ko nşe ti Idẹjọ omilẹ, bikoşe fila funfun ti a fi da a l'ọla, gẹgẹ bi a ti nfi fila oni kanrinkan pẹlu akisa olowonyọ didi m'ọrun, pẹlu agbada dudu bi ti ọlọfọ, da awọn akọwe agba Kotu ati isangbe wọn (Chief Registrar and their Deputies) l'ọla lalai nşe işẹ Lọya.

Mẹku bi obinrin, obinrin na si ni ọkọ ni Ido, o si bi Ọrẹluyi ti o jẹ Onitana lẹhinna, Ọrẹluyi bi Ogunfunmi, bẹni nwọn bi ara wọn titi ko to kan Ajọsẹ ti o jẹ oye Onitana nisisiyi. A tilẹ gbọ pe ẹlomiran ninu wọn ti a ko daruko rẹ nihin jẹ akura, şugbọn awo gbe awọ ni'gbọnwọ.

Onitulẹ, eyini ni ẹniti o nşe etutu ilẹ ni oruko oye ti nwọn sọ di Onitana nisisiyi, oye aborişa ni, ki nşe Idẹjọ, nitorina ko le ni ẹsẹ ilẹ kanşoşo fun ra rẹ gẹgẹ bi oloye ayaşebi eyiti Aromirẹ ba fi da a l'ọla.

Bi Ajọsẹ ko rẹni pitan fun ni o, bi o si fẹ lati fi agidi şe ti nu ara rẹ ni o, awa ko mọ, ki o to pe ọpọlọpọ enia lẹjọ, ki on papa to bọ sinu apoti ẹjọ lẹhinna, ki o to bẹrẹsi sọ isọkusọ bi ẹja l'odo, ati ọrọ alufanşa miran bi iru eyiti o sọ si Bajulaiye, ati Oloye Ọjọra.

Ajọsẹ fẹrẹ le wipe on lo ni gbogbo Eko tan, şugbọn gẹgẹ bi o ti fẹ lati j'ogun buruku, bẹni eti rẹ gbọ itan buruku to.

Bi Esuru ti şe aşeju ti o tẹ lọwọ oniyan, bẹni ohun ti Ajọsẹ Onitana şe ko dun mo pupọ boya ninu awọn ọrẹ rẹ papa, lai ka awọn ti o d'oju ija ko.

A koi le sọrọ pupọ lori idajọ na nisisiyi, titi ọwọ wa yio fi tẹ idajọ papa; nigbana ni a ni ireti lati sọ si aşaran fun aşaran ko ye aran şẹ.

Emi ni ti nyin nitotọ,
ATARI AJANAKU.

---

## ILE-IGBẸ (PUBLIC LATRINE).

[ Lati ọwọ ỌKANŞOŞO-AJANAKU ]

Si oniwe irohin "Eko Akete"

Iba o!

Ninu iwe irohin Eko Akete yi ti ọjọ kẹta oşu *December* to koja lọ yi (1927) a şe wosika kekere kan sibẹ nipasẹ ọran ile-igbẹ (*Public Latrine*) ti o mbẹ ni Pedro Street lẹba ile ologbe Tom Jones, wipe ipo ti ile-igbẹ na wa ko yẹ fun ibẹ arara.

A si ladi abajọ ti ibẹ ko fi yẹ fun awọn Municipal, (*Lagos Town Council*) eyiti a si nwoye wipe nwọn a gba ọran inu wosika wa na yẹwo, lati şe gẹgẹbi a ti wi. Ohun pataki ti a sọrọ nipa ọran ni wipe, ki nwọn gbe ile igbe na kuro lori ibiti o mbẹ na, ki nwọn si şi ipo rẹ lọ si ibimiran ti o ba yẹ fun u.

Lati igba ti a ti sọrọ ile-igbẹ na, li a ti nwoye ewo ni awọn "*Lagos Town Council*" yio şe si i, şugbọn di bi a ti nkọwe ekeji nipa rẹ yi, a koi ti ri oye wipe awọn onilu ti a nfi ọran han yi ti şe paramu kan, gẹgẹbi oye ti a fi si iwaju wọn, nipa eyi lo mu wa lati kọ wosika keji ti oni, eyiti a si tun mura nisisiyi lati tun şi wọn leti, boya nwọn ko gburo ọran yi ninu iwe-irohin ẹwẹ boya ede inago ti a kọ ni ko jẹki nwọn kula rẹ, ti o ba jẹ wipe iwe-irohin de ọdọ wọn ati pẹlu bi nwọn ba si gbọ wipe a ba wọn sọrọ nipa ile-igbẹ yi, *Lagos Town Council* tabi Alabojuto ilera ilu, a fi nhan nyin wipe Ile-igbẹ (*Public Latrine*) ti o mbẹ ni Pedro ati Docemo Street lẹba ile ologbe Tom Jones, ko yẹ fun ibibi o gbe wa yi mọ, papa ti aseko yi, ki ẹ si gbe lọ si ibomiran ti o ba dara fun u, gẹgẹbi o ti wa ni ibiti ile-igbẹ na wa yi, o jẹ ohun inira fun awọn ara ilu ati fun awọn ara ilu ati fun awọn aladugbo ti o mbẹ lagbegbe rẹ.

Nitorina, a fẹ ki Town Council mọ wipe, bẹni ile-igbẹ ti a mbawi yi ko ye ni ibiti o wa nitoripe orun rẹ pọ lọpọlọpọ, o si yẹ ki a gbe lọ si ibomiran ti ki yio jinna fun awọn ẹniti o njẹ anfani rẹ, a sọ eyi nitori ailera ilu.

Şugbọn li a ko ba ri eye kan lehin wosika yi, nigbana li ao to şe e ni ọde Igẹsi.

ỌKANŞOŞO AJANAKU.

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.,
*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

AREMỌ FUN ỌKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o njẹ pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo arun ti ki ẹ ki ọkunrin ṣe abiamọ.

*N.B.*—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loṣoṣu—Iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.

*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic.

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B:—Not obtainable elsewhere.*

GBOGBONIṢE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ, ati oriṣiriṣi arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.
**Postage 2/6 extra.**

WHITE'S

## WONDERFUL BRAIN TONIC

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq.
41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra

N.B.—*Scholars should not be without it.*

EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe, awọn ti o nfi iwe ṣiṣẹ ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba ṣe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy for Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by
VICTOR WHITE, ESQ, *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos
"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.

*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

EGBOGI ILANA ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oṣu rẹ mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aṣẹ Ewurẹ pipọju, Ẹda ti o ba gbe Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyun Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to :—

MR. MOSES O. COKER,

Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

---

### GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specifie acts like Magic : has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

---

*Cable Address* :—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIREMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

**Indents House.**

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.



When replying advertisers please mention *Eko Akete*

---

# TO LET.

**One Splendid Pleasure Car**

No. L2754.

**Always at everybody's service at Tinubu Square.**

For Terms, Apply to:—

A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

## ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

### Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

—— : o : ——

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọm...
ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to k...
si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorişirişi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi a...
awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si ...
ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.


Printed at "Tika-Tore" Printing Press, 20, Market Street, Lagos, and Published b...
...ica at 24, Williams Street, Lagos, Writer and Lecturer.